Ọrọ agba

ỌPẸRẸKẸTẸ ọdagba, ìnu adamọ mbaje. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

Irohin Yoruba

Akiyesi

POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona.

NO. 119 WEDNESDAY AUGUST 5 — TUESDAY AUGUST 11 1964 KOBO META 3D

NI YOTOMI NI AWỌ WA

OJU WỌN REE O!

Ọrọ Olotu :

Inakuna tabua!

BI oju ba ri, ọnu a dakẹ ẹgbọn ki ise wipe ki a ri inakuna ati iwa wọmbia laifohun. O dabi emipe gbogbo aiye fẹwọ lcran nigbati ọgẹdẹ Ipinlẹ Iwọ Orun nra, ti Oloye Akintọla ati awọn baba ogun rẹ ni Kaduna ati Eko ro wipe o apọn. Awọn baba ogun nyọ yinkinni-yinkinni nigbati ibanuje nderi awọn ọmọ Oduduwa kodo lojojumọ.

O ju ọdun meji nisisiyi ti ọkọ awọn ọmọ Yoruba ti bẹrẹ irin ajo si ebute Iparun. Awọn wo ni o nu ọkọ na? Awọn oniwọra ọsẹla ni. O dabi enipe nwọn ti pinnu lati ba Ipinlẹ Iwọ Orun kanlẹ kerẹlẹ, ki ego rẹ si wọmi larin awujọ patapata.

ALHAJI Abubakar Tafawa Balewa ati Alhaji Ahmadu Bello ko fi pamọ rara pe awọn ni o ti Oloye Samuel Akintọla lẹhin lati tapa si aye egbe rẹ ati awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun ni ọdun 1962. Kini abọ gbogbo rẹ loni? Ọsi ropẹ ọrọ, laisa ropẹ itura nigbati inakuna ijọba di ogun ajisa ni Ipinlẹ Iwọ Orun. Bi ọmọde ba nge igi, agbalagba yio ma wo ibiti igi na yio we si. Igi ti Akintọla, Balewa ati Bello ti bẹrẹ si ge ni ọdun 1962 ti awo lulẹ. Abọ rẹ re o!

LARIN ọsẹ ti o kọja ni Oloye Akintọla tun yan awọn ọmẹwa (Alakoso ijọba) meje kun awọn Alakoso ijọba ti o pọ bi ọmọ yaasin ti o ti yan tẹlẹ. Pẹlu awọn ọmẹwa meje titun na, o di Alakoso Ijọba mọkandinladọta ti o wa ninu Ijọba Akintọla. Awọn ọmẹwa merin miran tun wa ni ipo gẹgẹbi Alakoso Ijọba. Ni apapọ, awọn ọmẹwa metaleladọta ni awọn asanwo ori, aṣegite, apọnmita, ọlọmẹlankẹ, agbẹ onikoko, alaaru, ajawota, mẹkunnu ati ọlọrọ nda ọjọ fun losoọsu.

LATI toju Alakoso Ijọba kan ni ọdun kan, o to ẹdẹgbata ponun (£2,000) ti o njade ninu apo Ijọba ti awọn asanwo-ori nda eru si; o to egbaaji o din irinwo ponun (£3,600) owo awọn mẹkunnu ti Ijọba fi ntọju igbakeji Alakoso Ijọba kan ni ọdun kan soso.

PẸLU afikun awọn ọmẹwa meje yi, egbẹgbẹrun ponun lọna ogbọn ati egbẹrin ponun (£30,800) ni o je adimẹru fun ajọ ti awọn asanwo ori nda fun ijọba lọdọdun. Iye owo yi to lati ko ogbọn ile igbẹhi fun awọn abiyamọ tabi lati ko ile iwe giga kan lẹkunrẹrẹ.

KO ha ni ya awọn enia lẹnu wipe ninu awọn arirebanije ọmọ egbe NNDP merinleladọta ti o wa ninu Ile Igbimọ Asofin ni Ipinlẹ Iwọ Orun wipe enikansoso ni ko iti ri ipo gẹgẹbi ọmẹwa ninu Ijọba Akintọla? Enikansoso na ti i ṣe egbẹ NNDP silẹ. Eyi ko ha gọnlọ nban? Nkan ko ha wa ninu 'maa do mi niso?' Ijọba yi ko lẹgbẹ ni orile-ede Naijiria ati agbaiye.

Wo oju ewe kefo

AWỌN ẸMẸWA AKINTỌLA

1. ???
2. Oloye Fani—Kayode (Igbakeji Olori ati Alakoso ego Ijoba Ibile)
3. Oba C. D. Akran (Alakoso eto Inawo)
4. Oloye A. O. Adeyi (Alakoso Igbokegbodo oko)
5. S. D. Onabamiro (Alakoso eto Ogbin)
6. J. O. Oshuntokun (Alakoso Idaghasoke)
7. Saka Layonu (Alakoso eto Ifiniloye)
8. A. Bello (Alakoso eto Aje)
9. Dipo Ogundiran (Alakoso eto Ile)
10. Okunola Adebayo (Alakoso eto Irohin)
11. S. L. A. Fajimi (Alakoso eto Arin Ilu)
12. J. O. Omitowoju (Alakoso eto Iloro)
13. D. K. Olumofin (Alakoso eto Eko)
14. Tunji Olowofoyeku (Alakoso eto Idajo)
15. J. O. Adigun (Alakoso eto Ipe)

AWỌN AMUGBALEGBE ALAKOSO

16. N.A.B. Kosoye
17. Adegbite Tinubu
18. E. B. Arewojolu
19. C. O. John
20. J. O. Omokowajo
21. S. A. Adeniya
22. J. L. Tifase
23. Ayo Ajibola
24. O. Olaitan
25. K. S. Adebesin
26. Z. A. Opaleye

AWỌN ALAKOSO ALAINISE

27. Oba Samuel Abimbola (Olowo ti Iwo)
28. Oba A. Adenle (Atoofa ti Oshogbo)
29. Oba A. Gbadebo (Alake ti Abeokuta)
30. Oba Olateru Olagbegi (Olọyọ ti Ọyọ)
31. Oba Adetunla Adeleye (Elẹkọle ti Ekọle)
32. Olubadan ti Ibadan (O sofo)

AWỌN IGBAKEJI ALAKOSO

33. E. O. Oke
34. O. A. Akinghoye
35. S. A. Sanni
36. A. S. Somotan
37. J. A. O. Ogunmuyiwa
38. J. O. Abiosun
39. O. Adelodun
40. S. O. Akerele
41. O. A. Borokini
42. I. O. Aniyi
43. C. A. Williams
44. J. G. Adesiran
45. J. L. Lawal
46. L. A. Ajimobi
47. J. A. Ajewọn
48. C. O. Olamigoke
49. K. O. Owonikoko

AWỌN ALASE IJỌBA N'ILE IGBIMỌ ASOFIN

50. Omo'ba Adeleke Adedoyin
51. S. T. Adelegan
52. R. A. Lana
53. O. Fashola.

Awọn alakoso Ijọba Akintọla di jaburata

Ijọba Iwọ-Orun Naijiria ti tun yan awọn Alakoso merin ati igbakeji Alakoso meta kun awọn Alakoso Ipinle Iwọ Orun.

Nwọn ṣe ikede awọn Alakoso titun na ni Ibadan ni ọjọ kerindilogbon osu kẹjọ odun yi.

Awọn Alakoso titun na ni Ogbeni S. L. A. Fajimi ti o ti je amugbalegbe Alakoso ni ibi ile Olutu tele ri nigbati awọn yan si ipo Alakoso eto abo ile. Oloye Olaitan, Ogbeni K. S. Adebesin, Alhaji Z. A. Opaleye si ipo amugbalegbe Alakoso.

Awọn igbakeji Alakoso titun ti awọn yan ni Ogbeni K. O. Owonikoko si ibi ise eto idaje, Ogbeni J. A. Ajewọn si ise eto Eko, ati Ogbeni C. O.

(Wo oju ewe kejo)

OLOYE (Iyafin) Hanna Awolowọ fi oju se mẹrin pẹlu ọkọ rẹ, Oloye Obafẹmi Awolowọ ni ọjọ kokandinlogbon osu keje odun yi ni ọgba ẹwọn ni Kaduna fun igba ekini lati ọjọ ti nwọn ti gbe Baba Layinka lati Eko lọ sibẹ.

Irohin lati ilu Kaduna sọ wipe lati owuro kutukutu ni awọn enia ti to si egbẹgbẹ ọna ilti ti o lọ si ogba ẹwọn na ni ọgọgọrọrun lati yombo Iyaafin Awolowọ. Bi o ti ye lọọkan

(Wo oju ewe kejo)

OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

COLLIRON

GIVES IRON

IRON

GIVES HEALTH

Colliron Iron Tonic gives you the iron you Need for a Strong Healthy body. Give your whole family Colliron to build their health.

EVANS

15/17, Breadfruit Street, P.O Bo. 2151, Lagos Tel 23688, 23689.

Ọrọ Olotu:

IDIBO MBỌ, ILERI ASAN NJÁ BỌ

LAIPẸ yi, ẹgb; awọn agbẹ melo kan ni Ipinlẹ Iwọ Orun kesi Ijọba Akintọla lati fi owo kun owo koko wọn. Pẹkipẹki ni a faramọ ibere wọn nitoripe bi a ba nsokun, a maa ritan. Eniti o ba se ni ibi pẹpẹ, ibẹ ni o gbọdọ ti jẹ. A ro wipe o jẹ idẹsẹ si Olọrun ati enia bi ọbọ ba ati inu igbo wa jẹ anfani ogun oju nja.

KI iṣe wipe awọn agbẹ ṣẹṣẹ nbere ẹkunwo yi ni. O ti bẹrẹ lati ọdun 1961 ti Oloye Akintọla ge owo tọnu koko onipo kini lati ọgọjọ pọnun si ọgọrun pọnun. Laiṣe ani ani ẹdinwo koko yi jẹ ọkan ninu awọn idi ti o fa rogbodiyan ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ọdun 1962 nigbati babasalẹ ẹgbẹ na ba awọn enia ti o ge owo koko na wi.

O ṣẹṣẹ fun awọn enia kan lati ma sẹ loni wipe awọn kọ ni o ge owo koko. Ṣe ọbẹ ti o ba sọnu ko si ẹnikẹni ti o ma nfi jẹ iṣu. Eku ti o da eyi silẹ ni a npe ni ẹda. Awọn ọdalẹ ti o parapọ sinu ẹgbẹ NNDP loni, ti nwọn nsọ kiri wipe awọn fẹran awọn agbẹ onikoko kọ lo ṣe awọn agbẹ kanna ni ẹgungun ẹhin ni ọdun 1961?

Oju ma ngba wa ti ni ọpọlọpọ igba ti a ba gbọ ọrọ ẹtan lati ẹnu awọn enia ti a ba ta ki a fi ra atupa, ti nwọn a tun ma polongo kiri wipe awọn ni ajitannawo. A ro wipe awọn agbẹ ti nilati kọgbọn nisisiyi ti nwọn ti tọ ile ọkọ meji wo. Bi awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ti nkigbe ko si, ko si to; sibẹṣibẹ awọn ọmọ wọn nyo. O ba tọ ki awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ma yo, ki awọn agbẹ si ma ru?

AWỌN agbẹ onikoko gbọdọ mọ wipe awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ni ọta wọn ekini nitoripe eniti o ba gba ounjẹ lẹnu enia ko ro rere si iru enia bẹ. Eyi gbọdọ to ero fun awọn agbẹ nigbati akoko ti idibo ba wọle ni Ipinlẹ Iwọ Orun.

ILERI aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ni Ondo laipẹ yi pe ẹgbẹ on yio fi kun owo koko ki iṣe ohun ti eti ko iti gbọ tẹlẹ ri. Ṣe on kanna ti o ge owo koko na ni ọdun 1961 lo tun fẹ da pada. Kini ohun ti eti ko gbọ ri nibẹ? Ẹbẹ kanṣoṣo ti a bẹ aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu nipe bi ko ba le fun aiye awọn agbẹ ṣe, ko ma salai fi wọn si aye ti nwọn wa ni ọdun 1961—iyen ni ọgọjọ pọnun fun tọnu koko kan onipo kini.

A ko ro wipe awawi kan tun le wa fun ẹnikẹni pe owo ti tan ninu apo Ijọba nitori owo ti ijọba ya ẹgbẹ oniṣowo NIPC, nitoripe gbogbo owo na ni Ijọba ti gba pada lọwọ ẹgbẹ oniṣowo na. Bi ẹnikẹni ba sọ wipe owo koko ko le to ọgọjọ tabi ọgọjọ pọnun nitoripe ko si owo, were ni agbẹ ti o ba gba iru ẹtan bayi gbọ. Mọto dọọmidọọmi bi ọkọ ofurufu ti nrin rẹgẹrẹ ni igboro, tani o ni wọn? Awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ni. Awọn ilegogoro lori eyiti nwọn ti fẹ gbidanwo lati ma na ika gun oju Olọrun, tani o ni wọn? Awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ni. Bi nwọn ba le ri owo lati ma ra mọto bọlibẹli, ti nwọn si nkọle kiri bi ẹlyẹ, njẹ ko ha tọna nipasẹ lakayẹ fun wọn lati ba Ijọba wa owo lati fikun owo koko awọn agbẹ arokokura?

ILERI babasalẹ ẹgbẹ Dọmọnu ko sai jẹ mọ idibo ti o mbọ laipẹ yi ṣugbọn eyi ha le ṣe Iwenumọ iṣe ibi ẹgbẹ Dọmọnu? Awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ti gbagbe wipe ẹniti o ba yagbe lo le gbagbe ṣugbọn eniti o ba fa igbẹ na ko le gbagbe. Ẹgbẹ Dọmọnu lo ba Ipinlẹ Iwọ Orun de ipo ẹhin ti o wa larin awujọ loni. Bi ẹgbẹ Dọmọnu ba fun awọn agbẹ ni ẹkunwo, ki nwọn dupẹ lọwọ Ọlọrun wipe ore-ọfẹ ni, bi o tilẹ jẹ wipe iye owo yowu ti ẹgbẹ Dọmọnu ba fikun owo koko na, ẹgbẹ Afẹnifẹre setan lati fi bi ogun pọnun kun. Ko si iye owo ti o le pọju fun awọn agbẹ lati gba nisisiyi nitoripe 'awẹ ti ba awẹ nilẹ', nitorina ki awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu dẹkun ẹnu fifọn.

IYANU

O YA wa lẹnu pupọpupọ pe Oloye S. L. Akintọla kede ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu keje ọdun yi wipe on ngbero lati ṣe irin ajo yika Ipinlẹ Iwọ Orun. Ohun ti o ya wa lẹnu nipe o dabi ẹnipe Oloye Akintọla ti gbagbe ohun ti oju rẹ ri ni akoko ipolowo eto ikania ni ọdun 1963. Bi o ba ti gbagbe ohun ti o ṣẹlẹ si ni ọdun 1963 ni Ilaro ati awọn ilu miran, ti ọdun 1964 nkọ? Rogbodiyan Oshogbo, Ilesha, Akurẹ, Ondo ati Ekiti nkọ?

OHUN ti o tun ya wa lẹnu nipe bi awọn aririnbanijẹ enia ba ntan Oloye Akintọla jẹ, o ha yẹ ki on na tun ma tan ara rẹ? Tabi Oloye Akintọla ro wipe Ipinlẹ Iwọ Orun ti tura fun on? Kaka ki o san fun Iya ajẹ ni ọrọ na, o nfi gbogbo ọmọ rẹ bi kiki obinrin, ẹiyẹ wa nyi lu ẹiyẹ.

OHUN ti o nṣẹlẹ ni gbogbo ipinlẹ nipe awọn Olotu ijọba lo nrin falala laisi Ifọiya tabi rogbodiyan ṣugbọn ti Ipinlẹ Iwọ Orun yatọ nitoripe ẹgbẹ Dọmọnu ti o nṣe akoso ijọba ṣe ajeji si awọn adibo; nigbana ọrọ ha dun lẹnu aṣiwaju ẹgbẹ ọsangangan na? O wu wa pe ki Ipinlẹ Iwọ Orun le ni Olotu Ijọba ti yio le rin falala laisi rogbodiyan ṣugbọn nigbati ko ri be ako? Bi ẹniti awọn ara ilu ko fẹ ba ni on yio da orin, tani yio gbee?

NIBO ni Oloye Akintọla fẹ lọ? Ekiti, Ẹgba, Ọyọ, Ijẹbu, Ondo tabi Ilesha ni? Bi o ba jẹ wipe asọdun ni ikede na, a jẹ wipe Akintọla ntan ara rẹ jẹ ni; bi o ba si jẹ wipe nitotọ ni, a ko ni ṣai kesi awọn ọlọpa lati gba Akintọla ni imọran lati duro de akoko tirẹ nitoripe ẹgbẹ Ọlọpẹ ati Alakuko lo gbede, ki iku paramọ, ki arun parada! Ki iṣe wipe ẹru mba ẹnikẹni nitoripe a mọ wipe ọrọ awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ko le yi eṣinṣin lasan lọkan pada ṣugbọn nitoripe gbogbo ibiti awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ba de ni rogbodiyan ti mbẹ silẹ. Ile ỌLỌWỌ ki Iforo.

Alapara Ibadan

Alapara: Ẹ ku Iyalẹta

Olotu: Mo dupe oju to tun ra ri pẹlu ayọ

Alapara: Emi paapa ti ba Ọjẹ lọ ni ko jeki a ti rira pelu yin nitoripe mo feran lati ma fi itan adiẹ jẹ eko.

Olotu: O gbagbe pe alagbaa ti nfi itan adiẹ jẹ eko enu ojo meje ni imọ.

Alapara: Nigbati emi paapa ti nmura sile lati esi pe egungun mi yio jade sugbon owo ko si enia ko sunwon ni mo se ti ẹku egungun mi si ori aja.

Olotu: Mo ranti pe gbogbo elegun ti o ba gba lati ma se egbe Alagbara gbọdọ ni owo lọwọ, Tabi be ko?

Alapara: Eleyi mi jinna si otito kẹ, e ri ko mọ pe owo ... ni nwọn fi nmọ ase lori. Elegun kankan ko le ri gba bi o ba je pe on paapa fi ti owo re sile.

Olotu: Ni iwọ na ba di jẹunjẹun kaiye?

Alapara: Kini emi ko ni roki si nigbati ko si Ise ti ko si abo 'ẹnitiko ba le ṣe egungun emi yio sa se akebọ jẹ nidi osa olosa.

Olotu: Ejọ tani eleyi ha iṣe?

Alapara: Ko si ẹniti mo ri ba wi bi ẹniti o fi ọmọ fun ọkọ ni oru, ti ko jẹki ile o mọ. Ki ise enyin na ni e fun Igbarra ni oti Oyinbo mu?

Olotu: O ko mọ pe igba kan ki ito lọ bi orere.

Alapara: Igba na ni onigba ka oba ti o je ti a fi iyun ko ile ati eyiti o je ti a fi iyuni kọ le, olukuluku na ni o nigba tire.

Olotu: Igba tani a fi iyun kọ le, igba tani awọn enia fi iyun bo'le?

Alapara: Ki ise Ibadan nikan ni mo ti ba ẹlẹbọ kẹ bọ jẹ kẹ, mo tun togbẹgbẹ lọ si Ọyọ pẹlu lati lọ ba wọn ṣe egungun sugbọn ohun ti mo ba nibẹ ko sunwọn.

Olotu: Kini alabapade egbe Domonu ko rekọja ilu Ibadan?

Alapara: Tani nje aja ni Mọsalasi? Tani mọ oloko egbe Dọmọnu ni Oyo? Emi ko fẹ gbe ara mi lenu jo nitori egbe jeunjeun yi, ohun ti enu yio je ni mo nwa kakiri ni temi. Mo tori amola ba won gbe oku re Oyo, mo tori iyan ba nwọn gbe odo re Ede.

Olotu: Bẹni ti ẹ ri, bi enia ko ba ni owo ti ko si ni ogun ko ye ki oju ma ma pọn. Kini yio fi ma da eru ba aladugbo rẹ?

Alapara: Ẹnyin ko mọ pe orisa bi ẹfun ko si, ojojumọ ni o ngba ẹbọ. Bi mo ri aja lori ogun dede enu re nibe?

Alapara: Ni ojo ti mo de ibẹ ni awon egbe Domonu fe se ipade pataki kan: egungun won paapa jade lojo na sugbon kiamosa ni awon olopa gbe egungun Domonu wole. Asiwaju egbe na ni oyo fese fee nigbati oro ko wo mọ.

Olotu: Eleyi ni pe ihale mi lo se, enu ki i ko eyikeyi.

Olotu: Njẹ iwọ ko le je oda bayi?

Alapara: Oda ha ti jẹ lẹnu mi nigbati emi ko te were m'ẹba?

Olotu: Eleyi ni pe akoko igba egungun ti se enu re bayi?

Alapara: Koda itan aja meje ni alagbaa fun mi nigbati mo lo ba ni ile re ni oke Jegede.

Olotu: O ko tile fenu kan bi nwọn ti ṣe egungun ni Ibadan Tabi iwo ko si nile ni?

Alapara: Hẹu, bi enia tilẹ de mi sinu ago adiẹ emi ko le ma ba wọn se egungun ni Ibadan. Ti odun-ni tilẹ yatọ si gbogbo odun egungun ti o koja.

Olotu: Kini iyato ti o wa ninu re? Sọ fun mi ki ngbọ

Alapara: Ohun ti o je iyatọ ti o si njọ mi loju nipe nigba Iwasẹ awọn bi Ọjẹlabi Ọjẹwumi ni mo mọ pe o nṣe egungun ṣugbọn nisisiyi Raimi ati Adisi Akinloye na nṣe egungun ni Ibadan nisisiyi.

Olotu: Nitori kini awọn enia wọnyi se di eleguagun?

Alapara: Ko si ohun meji ti awon enia se ndi elegun ju ṣe-a-ri-mi oro oselu won lo, bi awon Ojelabi paapa ko ba le se egbe "wa mori-wa morun" egbe Dọmọnu, kia ni aṣọ egungun re 'eku' yio bo lori re lati ọwọ awon ọlọpa ibilẹ pẹlu ase awon "alagbara".

Olotu: Bi emi ba tilẹ ni egungun temi? emi ki yio se egbe oselu kankan. Kaka ki ase egbe, emi ko bikita ki nkuku pa aja ni je ninu ile mi fun awon enia ni. Ọrunmila paapa yio gba ẹbọ ju ki ntele awon jeunjeun oselu ti ko lẹsẹ nilẹ yi.

Alapara: Bi o ba sọ bayi niwaju awọn ọlẹ oṣelu, kikun ni nwọn

(Wo oju ewe keje)

ALAPARA IBADAN

JẸKI ARA RẸ WA NI ILERA ATI AGBARA

Nigbati o ba ni iwora, ali mara agbara tabi ni ara rẹ tabi otutu inu, ati aiya, lọra Ipara Mentholatum ki o fi pa a kankan ibiti o nroẹ lara. Iwura na yio lọ ni kiakia. Fi die pa inu rẹ, otutu re yio lọ ni kiakia. Mentholatum nse iṣẹ ni kiakia pẹlu agbara Idan, Agbayanu, agbayanu Mentholatum.

ATURA—FAWOSE—IWOSAN

Jẹki Mentholatum wa ninu ile rẹ nigbagbogbo-ra ide tabi agolo kan loni

BERE FUN OJULOWO MEN-THO-LA-TUM

MENTHOLATUM

OGUN IPARA TI O DARAJULO

Awọn ti o nṣe ni
Mentholatum Company Ltd (Est. 1889) Slough, England

Ẹgbẹ Akintọla fọnka L'Ọyọ

OLOYE A. AKERELE

OLOYE P A A'olabi ti ise okan ninu awon asiwaju egbe Domonu ni Ọyọ fese fẹ pelu agbada rẹirẹi laipẹ yi nigbati awon enia ilu na fariga mo lowo ninu ipade ti egbe Domonu pe laipe yi.

Lehin ti awon enia ti o pe ipade na ti duro fun bi wakati meji ti nwon ko ri opo enia ni nwon ba bere ipade. Ko ju bi ogbon iseju lehin ti nwon ti bere ipade na ni awon enia kan be jigan bi ekun wo ipade na lati so fun awon enia ti o pe ipade na pe egbe Domonu ko le ri idi joko ni ilu Ọyọ.

Bi awon asiwaju egbe Domonu na ti ri awon enia na pe nwon ko gba gbere ni nwon ba fese fe. Awon enia kan ninu won gbagbe lati mu fila won nigbati awon enia kan ninu won gba oju ferese sa sita.

Awon asiwaju egbe Domonu na so fun onirohin wa lehin ti ipade na ti kuna pe awon yio so fun awon ọlọpa nipa ohun ti oju won ri na.

Bayi, awon enia ilu Ọyọ ti faake kori wipe awon ko ni ni ohunkohun lati se pelu egbe Domonu.

Ọdaran yan atimọle

Okunrin kan, Amusa Mustafa, eni odun mokandinlogoji adugbo Ishodo Ijebu-Ode ko je ki eni kokan duro fun on. [illegible] ki won fi [illegible] niwaju ile ejo kekere kan ni Ijebu-Ode laipe yi nigbati o [illegible] ipania fara ti nwon fi kan an, o gba lati duro si atimole di akoko ti awon yio tun ejo re.

Bi o ti wi bayi tan ni adajo Oloye Joshua Oshinbogun so fun wipe o le se ohun ti o ba wu u.

Esun ti nwon fi kan nipe o pa okunrin kan Mojidi Sunmola lara ni ojo ketadinlogbon osu keta odun yi ni adugbo Ishodo.

KỌBỌ MARUN GBE OLE SẸWỌN

Ọkunrin kan, eni odun mejilelogun, Shehu Ganiyu ti ko ni iṣẹ lọwọ ti o ji kọbọ marun (5d) lọwọ awon ọmọ ile iwe meji ti fi ẹwọn ọdun meji jura.

Ọdaran na so fun ile ẹjọ pe aini iṣe lọwọ ti ko si ona ati jeun mọ ni o sọ on di ole.

Ọdaran na ko ni ibugbe kan rara. Lehin ti adajọ ti ju u si ẹwọn ọdun meji, o tun ni ki nwọn fun ni ẹgba mefa ti o gbona.

Awọn obinrin fariga mọ Igbimọ Ijẹbu lọwo

EGBE awon obinrin onisowo Ijebu-Ode (The Marketing Women Association) ti so ninu ipade nla kan ti nwon se ti aimoye egbe awon obinrin na se ni Ijebu-Ode laipe yi pe awon ko ni igbekele ninu Igbimo-Afunso Ijoba Ibile Ijebu-Ode ti o wa labe akoso egbe Domonu.

Bakanna ni awon egbe Obinrin na tun so gbangba pe awon ko ipinnu Igbimo Afunso na ti o ni ki gbogbo awon obinrin maa le aworan won keke meta mo iwe ibere fun aye ipate ninu oja.

Nwon tun fi esun kan Igbimo na pe nwon nse inunibini si awon enia ilu.

Ọmọba'binrin Towobola Odutola so ni ipade na pe "iwa ika ni Igbimo Afunso na nfi ba awon enia lo".

O so siwaju pe gbogbo ase Igbimo na ni awon ti npamo lati ibere odun yi sibesibe, "Igbimo na ko dawo duro nipa fifi iwa irenilorba ba wa lo".

Awon obinrin na ni awon faramo ipinnu Igbimo Afunso na pe obinrin kan ko gbodo ni ju eyo ile ipate kan lo ninu oja.

Ki ipade na to gbese awon [illegible] enia [illegible] lati ri Oba Awujale Ijebu-Ode, oba Sikiru Adetona lati so fun ki o se atunse [illegible] Igbimo Afunso na pe ki awon obinrin maa fi aworan won meta si iwe igba ase.

[illegible]

'BALEWA GBỌDỌ GBA IJỌBA AKINTỌLA'

EGBE Ọdo Afenifere Ekiti ni Ibadan (Ekiti Parapo Action Group Youths Association Ibadan Branch) ti kesi Olotu Ijoba Apapo Naijiria, Alhaji Abubakar Tafawa Balewa pe ki o yara kiakia gba Ijoba Ipinle Iwo-Orun lowo egbe Domonu nitori itapa si ofin, itenilorba, rogbodiyan ati ifemi sofo ti o ti kari Ipinle na nitori aigbajumo ati aimose Ijoba egbe Domonu na.

Awon omo egbe na wa fi siwaju pe ohun ti o je mimo fun gbogbo enia ni orileede yi lati iwon osu die sehin nipe awon janduku egbe Domonu ti bere si da Ipinle Iwo-Orun ru, ti nwon ko si fi enia lokan bale. Iwa idaluru ti koja ala tobe ti emi gbogbo awon ti o wa ni Ipinle yi fi wa ninu ewu, ti enikeni ko le rin laifoya mo.

Nwon tun fi kun pe ohun ini ti o ti sofo lowo awon janduku egbe Domonu na ko lonka.

Akowe ikede egbe na, Ogbeni Akinyemi Olugbade, wa se itokasi ninu ikede re ti o jade ni ojo kokandinlogbon osu keje odun yi ni Ibadan pe gbogbo aisedede ti o wo Ipinle yi lati owo Ijoba egbe Domonu ni Iwo Orun ti ko aisedede nlanla ba eto idagbasoke aje orileede yi ati Ipinle Iwo Orun ni pato.

O wa pari oro re pe oti di oro dandan ki Alhaji Balewa gba ijoba Iwo-Orun ki awon enia Ipinle na le rin ninu elo won gege bi o ti se wa ninu akosile ofin orileede yi.

Asoju Ọdọ Ọlọpẹ lọ si Ipade Agbaiye

Ẹgbe Ọdo gbogbo agbaiye (The World Assembly of Youth) ti fi iwe pe Ẹgbe Ọdo Afenifere Naijiria lati wa si ipade Ọdo gbogbo agbaiye ti nwon yio bere ni ilu Amherst ni Massachusetts ni orileede Amerika ni ojo kokandinlogbon osu keje odun yi.

Ogbeni S. A. Shitta Bey, akowe ikede egbe Ọdo Afenifere Iwo Orun ni yio se asoju egbe odo Afenifere lo si ipade na.

O fi ile Naijiria sile gba ti ilu Paris rekoja si ilu New York ni ile Amerika ni [illegible] Aiku [illegible] ojo karundinlogbon osu keje odun yi.

Koko oro ti awon yio se atupo le lori ninu ipade na ni ipa ti odo agba oke ninu ifokanbale ati alafia agbaiye [illegible] Ogun [illegible] ho [illegible] si yi."

[illegible]

AWON ỌMỌ ẸGBẸ ỌLỌFẸ MORIBỌ

SAKA ni adie ba lati oko eemo. Ile ejo kekere kan ni Ibadan ti da awon omo egbe Afenifere medogun sile lalafia laipe yi lori esun ti awon olopa fi kan won pe awon di ihamora ogun, awon si nrin irin arede kakiri ninu igboro ilu Ibadan. Ni adugbo Ayeye ni Ibadan ni awon olopa ti mu awon enia na ni ojo karun osu kerin odun yi.

Lati ile ise olodari ipejo fun Ijoba Ipinle Iwo Orun ni ase ti jade wa pe olupejo fun ijoba ko ni ba awon enia na se ejo mo.

Awon okunrin na ni: Taiwo A'abi, Tunde Ogunleye, Simpson Falade, Sikiru Adeyale, Salawu Balogun, Mosudi Balogun, Michael Fabunwo, Michael Adikoye, Jacob Badejo, Joseph Olowokere, Enoch Ogundipe, Raimi Adeyemi ati Abubakare Obisesan.

FEMITONE

Femitone je egbogi asiko pataki fun awon alaboyun wa awon ti nto ọmọ lọwọ ti o ni ohun elo ti nmu eje ati ninu ara ati eyiti ki jeki oju su Vitamins. On tun eje se, o nmu eje pọ si ara, o nle majata lọ, o si nfun ni ni ilera, o njeki omo ti o wa ninu oyun dagba pelu ilera. Gbogbo awọn eya ara a si pişe dede nigbati o ba nlọ. Bere lọwọ aladugbo re ti o nta egbogi ati ni:

ANJORIN CHEMISTS LIMITED,
318, Herbert Macaulay Street,
SABO YABA. Telephone: 44288.

Korẹ ati Awọ-ara ti ko dara yio san larin wakati merinlelogun

NIXODERM je egbogi apoju pataki [illegible]

[illegible]

NIXODERM

Ọdun Ṣango kọyọyọ ni

EYIOWU Elegunsango pa itu m je ti ọde ọpa ki en'a ta mọ pe o to mu lọ si ọja ẹgun ni ọjọ Aje ti Ise ọjọ katadinlogbọn osu keje ọdun yi. Orisirisi idaraya ni Elegunsango ṣe, ara awọn idan ti o pa ni fifi ọwọ asoro lu awọn ara re, o bu omi sinu apere lailọ, o tu bẹẹ fun awọn ara re, o bu omi sinu apere laijọ, o ti bẹẹ funfun ra ima, akọle orisirisi ni han awọn re, ṣugbọn o ṣe bẹẹ, ninu awọn idan na ni aigbati awọn ori gba ile ti awọn si irun sooso kan mọ ile ti Ṣango joko. bẹẹ re ti o si ko ẹre kuro nkẹ.

Ile Abiọdun ni Isale—Ọyọ ko gba ere, ọdukuluku ma pẹlu isọti ti re kakiri gbogbo adugbo Ọyọ lati wa ba ara wọn ṣe ọdun na ni ile Baale onisango, Oloye Oyedun.

Orisirisi iseri ni awọn enia ti o wa pẹlu ere orisirisi bi awọn arugbo ti ko ẹgbe lọ, beni awọn adelebo obirin, bakanna ni awọn ọdọmọde. Nwọn ja ewe lọwọ, awọn miran mu aṣọ lọwọ lati fi ma oju Ṣango.

Eyiti oTpa ni lerin ni orin ti awọn arugbo ti o mu opa lọwọ nkọ bayi "kini yi dun, mo rele oloko, kini yi dun mo rele oloko". Ọrọ yi mu mi bere lọwọ awọn iya arugbo na pe kini itumọ orin na? ọkan ninu wọn ti sọ fun mi pe gbogbo awọn ti awọn nkọ orin yi ni Ṣango fun ni ọmọ nitori eyi Ṣango ni awọn npe ni oloko.

Awọn miran ti Iyawo Sulọla Aike je alori fun ten nkọ orin ti wọn bayi pe "Alapadupe, Ṣango ma pa mi pa iyo mi alapadupe, Abebi ma ba ọ dele, Abebi ti bọ ni Ṣango lọ, ma ba ọ dele" ati bebe lọ.

Lẹhin eyi ni mo wa ba awọn onisango wọ ile Awo won lati lọ se iwadi awọn ọrọ die lọdọ Elegunsango. Mo si bere idi pataki ti nwọn fi nse ọdun Elegun Sango. Eyiowu Elegunsango sọ fun mi pe Ṣango ni o te ilu Ọyọ do, on na ni nwọn npe ni Ọba Koso, on ni ise Alafin Ọyọ akọkọ. Oruko re si ni Afọnja.

Ṣango Abiodun je tele. Lẹhin eleyi ni o wa kan eniti o wa lori re loni, Ṣango Atiba.

Mo tun te siwaju si po kini ko jeki nwon ma se ọdun Elegun ninu ile ọba? O dahun "ibiti mo wa yi je ibiti gbogbo ọba Ọyọ ti i je niborina ki ise ita lati tun gbe lọ si ile ọba. O si tun dahun ibere kan ibe ni Pe ọkanugba.

O tun fere mi pe eniti o wa lori oye na n'isisiyi ni o je ikeji awọn ti o ti nje oye na, o si da oruko wọn ni tẹlẹtẹle bayi. Tẹ-

Lati ọwọ Ganilaw

ti mo bi bayi pe "Nje awọn nsi oye na kakiri ni Ọyọ tabi ajewe ni? O ni ile meji ti o nnmo ara won yi ni awọn ti ma nje oye na ki ise ajẹkiri. Nwọn si npe mina. Akinola, Koleoso, Latunde, Adesina, Ladele ati Oyedun eniti oye na wa lọwọ re loni gegebi onamugba.

Lẹhin ti ibere akoko pari ninu ile Awo ni awọn emewa re gbaa, ti nwon ni oriki Ṣango ni ọọna mejo bayi.

Ida ti Ṣango fi pa ni ko to nkan

Aba si sodan, a bẹ ni sosẹ

Peape bi awa a ti Isode bi ologbo

Archumo bi owa

Okunrin ni okunrin nai

Ti nwon nbọ mbọ wa

Apiki magba o ala

Ara bi owo ile ijala

Archamo bi owo

Oju ko to bi Ṣango gbe

Sulọla Onisango ni o nfi ijo peta bi kokoro ninu aworan yi pẹlu awọn enilu re. Awọn arugbo paapa ko da ijo jijo na da. Bi orin ti nbọ lenu awọn agbagba beni awọn ewe na nso winriwinrin ti won lenu.

'IROHIN YORUBA' DI W'URA' TETE RA TIRẸ.

Ọkan ninu agbara Eyiowu Elegun Ṣango ni ẹnwọ ninu aworan oke yi. Nwọn ri igi ti ilu asoro wa lori rẹ mole, o si joko ni ori rẹ laifarapa ti ẹnikẹni.

Ilu asoro na ko da idi re lo, beni Eyiowu ko si se oju bi eni pe ohunkohun wa ni idi on. Ere na kọyọyọ.

NOW—ROLLS-ROYCE 707s ON THE LONDON RUN



Eto irinajo ayarabiaṣa ti ojojumọ

NISISIYI oko ofurufu titun ti a npe ni Rolls-Royce 707 ti wa fun awọn ero ti nlo si Londonu ati awọn ile Oyinbo. Rolls Royce ti a mọ jakejado aiye fun ero ti o dara julo ti o se ero ti a nlo ninu oko ofurufu yi fo bi eiye. Fun igbadun ati itura nigbati o ba nrin irin ajo ninu oko ofurufu ayara bi ... Travel Agent re tabi ki o bere ni Nigeria Airways Booking Office ti o wa ni Broad Street, P.O. Box 136, Lagos (Telephone 24811) Bank Road, P. O. Box 11, Kano (Telephone 3891) tabi awọn ile ise oko ofurufu ni agbegbe re.

NIGERIA AIRWAYS

NIGERIA'S NATIONAL AIRLINE

yin bon

Etu ian, etu o tan ma da kun yinbon

Egungun ori ite Onaso

Okọ mi ijanu aiye

Kamwo bi a le

A da maru ateghe wara agbagba

Ọkọ mi mo na mi

Ọrọ re ko se fi na ọmọ

Eru Ṣango ma nba mi

A to agbalagba bu a bẹẹ ẹ kanbu

Oriki yi po, ko si ni aala; a fi eniti o ba fi eti gba

... ni Ọyọ

ni yio mọ bi ariki Sango ti se pọ to, bi ọkan ti npe tire beni omiran tun ngbe tire pelu okan-ko-jọ-kan.

Sugbọn nigbati mo bọ sita lati inu ile Awo ni mo tun kan awọn omode wewe bi iyan ati okun ti nwọn ja ewe lowo, ti nwọn njo bi kokoro. Iran awọn na dun wọ ni otitọ bi Elegunsango pa a ko ba ko se ohunkohun.

Ara orin ti awọn omode na nkọ nyi "Irọ lẹ npa

KILELEYI O ?

Okunrin ju ọkunrin lọ nitot ; beni agbara si ju agbara lọ.

Eyiowu Elegunsango ni Oyọ fi eyi han gan.

Aworan ti o wa ni ọwọ ọtun yi sọrọ fun ara rẹ. Eyiowu fi itin asoro bi esẹ baba kan ati abọ da abọn ara rẹ lu laisi ejẹ tabi irora. Idan na kọja afẹnuso.

Sango ko le pa tun, irọ lẹ npa Sango ... ni a ba ila, a ko mọ eniti o ko, iro le npa Sango ko le pa tan Akowe gbogbogbo abogibope ilu Ọyọ, Ọgbeni Adeniji Adisa ti o mo oni pelu Onifoto mi yika gbogbo ibiti nwọn ti abọ sango.

Adeleke Akanji ti se akowe onisango patapa ko fi wa sile lẹsẹ kan, on papa tun fun wa ni awọn alaye lori ọrọ ti olori onisango so fun wa.

Ki oto ma lọ si ibiti nwọn yio ti gun egun ni a ti de ile olori gbogbo abogibope ilu Ọyọ. Oloye Daro Atanda, o fun wa ni adura pe ki a ma lọ, alọ yio dara, abọ papa yio sanwon.

Ara awọn Oloye Sango

Bakanna ni awọn balebale tun se ara won jo sibi kan, ara won ni Oyewo, bale onisango, Alabi, olori onisango ati Ojo Ekoro onisango.

Enni o fi aye wa pe lati ilu on Ijebu-Igbo ni on ti wa ti'a ow ti awọn Oloye Ogboni lọ ni Balogun Salin. Bayi ni Sango se pari gbogbo awọn eto re ki o to bo si igboro pelu ọke aimoye enia. Irohin ko to afojuba.

ati awọn enia patakipataki ti o wa nibẹ pelu Oloye Oyedun, Balẹ Koso ni Yaye. Adetona; Ogunniyi, Alapinni; Ogundare, Alaso; Ojo Oyero; Ajag'bon Atunwa, Ogi Magba; Raji Anigilaje, Oluwo Ogboni; Bakare, Oluwo; Elemoso; Owolabi Jimoh, Apena; Bello, Olowu Atiko Ola Olofin ni Eko; Iyaafin Oyewọle, Iyalaje ...; Sebatu Adedoyin.

Aworan yi ni igbati Eyiowu Elegun Sango pari gbogbo idan re ti awọn oloye Sango si nfi ori bale fun un, nibe ni o ti gbe wure odun ati siso ohun ti Sango nfe lati owo won. Eyiti yio mu ebọ won yan peregede.

Iwe Irohin Dọmọnu dì afọju

O JE ọrọ afọju ti o afọna han afọju nipa ọrọ ti olotu Iwe Irohin Domonu kan sọ laipe yi wipe ki Akintola ko awọn ọlọpa Naijiria kuro ni Ipinle Iwọ Orun. Eyi je ọrọ alaimọkanse ti ko si mọ bi eto iselu Naijiria ti nlọ si. Nitoripe ko si agbara kankan lọwọ Olotu Ipinle kan lati kọ ọga ọlọpa Naijiria.

Ena awọn jekojeko ọlọpa Ilulẹ ti Iwọ-Orun ni awọn Akintola lagbara lori re.

Nkan pataki ti o wa ni Iwọ—Orun bayi ni wipe titi ti Igbakeji Olotu Iwọ Orun ti o ko awọn janduku lọ si Ile-Ife yio fi jẹjọ ọmọ ti o ku lẹhin re, ko si aye fun ọga Ọlọpa kankan lati kuro ni Ipinle Iwọ - Orun. Ise wo ni Olotu iwe irohin egbe Dọmọnu nfe ki awọn ọlọpa ti se ti o mọ fun wọn lehin igbati awọn digbolugi egbe Dọmọnu ti ba ile onile je, ti nwọn si ko eru eleru lan ni Ile Ife, ti nwọn nsa lọ si Ibadan?

Nkan ti o jọ ni loju patapa ni ọrọ Ọgbeni Gbadebo ti Olotu alailanu yi tun nso. Bi enia kan ba ta ibọn mọ bi ogun enia larin ilu losanganga pelu ero u wipe on je ara ile Olotu Ipinle kan ati wipe gbogbo agbara wa lowo on, ko ye ki ọlọpa mu bi?

Ọrọ yi tubọ fihan gbangba si awọn enia iru alaibikita

ati ma ati won, eyi ti je nka ti o afan won ni enia agba ofo ti ima ati enia sinu ipafun. Naijiria gbogbo enia lo ti gbo nipa eto ti awọn ... eyi ti awọn egbe Dọmọnu ti nse lati ko wo fun awọn digbolugi ki nwọn si ma kakiri ilu ... ti nwọn ko oruko ọlọpa nimaju se lati le mu da gbogbo enia lamu kakiri gbogbo Ipinle Iwọ-Orun. Gbogbo ọmọ alaiye lo ti simedo lati ma wo gbogbo bra ti Domonu yio ba da.

Ju gbogbo re lọ, nkan ti ko jẹki era Dọmọnu ba enikeni mọ ni wipe nigbati afọju ba

Lati Owo Ibi Isẹ Irohin Egbẹ Alakuko

ati odajo ... ti Olotu Iwe Irohin egbe Domonu yi je, nitoripe o ye ki o ti ri tabi ki o ti ma gbo nipa rogbodiyan ti gbajade lesati adajo Adeyemi ti da sile. Gbogbo awọn egbe Amofin patapa lọ ti lodi re. Gbogbo nkan ti ko ba dara tabi ti o ba lodi si ofin ni o ma ndafa loju egbe Domonu, sugbon nwọn igbati enia ... ko ba je nkankan loju egbe Domonu, ... loju ọlọpa ati afaiye ... lati lsafẹ to.

Nkan pataki ti mo ... si wipe o ma ndun mi pe awọn omo egbe Domonu ki ima ti ara won gegebi gbogbo enia ti afọna bo afọju, ipa ipa run ni gbogbo won nlo. Nitorina lẹba die loku bayi ti egbe Domonu yio mo ara won ni alaseju ti nwon yio si f'ebo jura.

IROHIN AGBAIYE

LUSAKA

Awon merinla ni o kugbe, ti awon awon metadinlogun si farapa rekoja ala ni ilu Lusaka nigbati awon olopa kolu awon onigbagbo ilu na lakoko iwode kan ni Ipinle Ariwa Rhodesia laipe yi. O pa kan wa ninu awon ti o farapa ni akoko isele na.

BELGRADE

Awon osise merin ni irohin kan ti o jade ni ilu Belgrade laipe yi fi ye wa pe o ku, ti awon merinla si farapa ninu ijamba bombu kan ti o tu apakan ile ise epo ti o wa ni BosankiBrod ni arin ilu Yugoslafia ka. Bakanna ni awon enia meji miran di awati sibe idagiri ile na.

TAIPEH

Gbogbo awon mejidinlogun ti o wa ninu oko afurufu C 46 ti orilede Taipeh ni irohin fihan pe nwon ku gbe nigbati oko na fori so oke kan lakoko ti oko na bere irinajo re ni ilu Gusu Taiwon ni orilede Taipeh ni ojo kerindinlogbon osu keje odun yi.

PARIS

Okunrin, olutoju ile ise kan ni Paris, Ogbeni Hugo Kellner sesi dana sun ile ise meta lakoko ti o fi ina si adogan idana re sugbon ti ina na ga fo mo epo moto ti o nfi nu awon ero ise ni ile ise O nse iloju na ni Paris laipe yi.

LONDONU

Ile Igbimo Asofin Ijoba ile Gesi ti se ipinnu iranti ati idupe fun ise ribiribi ti Ołola Winston Churchill se fun Ile Igbimo na ati fun orilede Gesi lapapo Olotu Ijoba ile Gesi, Ołola Alec Douglas Home ni o gbe aba idupe na jade ni ile Igbimo ni ojo kejidinlogbon osu keje odun yi. Gbogbo awon omo Igbimo nil o si fi ayo gba aba ati ipnnu idupe na.

SYRIAN

Omo ogun ile syria kan so ni ile ejo awon Ologun ni ilu Beirut laipe yi pe on wa si ilu Lebanon ni bere odun yi lati lo pa omo ogun ile Syria kan ti nwon ti da sile nitoripe o lodi si ijoba ile Syria ti o wa lori agabayi.

Ibukun ni fun Awolọwọ

OHUN ORIN — 1. IGBAGBO, Mia temi l'Oluwa.

1 Ibukun ni fun Awolọwọ
Eni O'oran yin, lati gba wa la
Kuro ninu'oyi yi ati Ibanuje
B'emi AWOLOWO wa ifo'ya kosi,

2 Awon 'dale gbima nitori Owo
Nitori ipo, nwon gba Awo s'ewon
Oluwa wa ti to, p'olọ yio leke
Ọrọ t'Oluwa sọ yio bori dandan

3 Gbogbo enyin, ọmọ Yoruba
E b'oju w'ehin W'ohun AWO ti je
O sọ Iwọ-Orun, di ile Fadaka
Eyi nikan to ro, E je ka tele

4 Nje b'ohun gbogbo ti nyise ire
Adun n'ikoro onje li ogun
B'oni ile koto, sa ko pe mọ,
Gbona orin 'segun yio ti dun to,

Bayo Oyefusi
EBUTE-METTA

Ọtẹgbẹyẹ pari Ẹgbẹ Olomi

Ẹgbe osise ati agbe "Socialist workers and farmers party" ti pinnu nibi ipade ti asiwaju egbe na, Dokita Tunji Otegbeye se ni PortHarcourt pelu awon omo egbe re pe awon yio sise po pelu egbe Alakuko ati Afenifere ninu idibo Ijoba Apapo ti nbo yi.

Dokita Otegbeye so pe egbe on rope ona yi nikan ni o le mu Ijoba wonbia, arirebanije ati awon amunisin enia dudu parun, ti yio si fun awon egbe itesiwaju, kire-o-kari ati kire-je ki emi-je bori dibo na.

Classified Adverts

Ko yẹki up'ofo nile aiye

A ki ... Aiye wa Tunsi. Bi aba ti pada, akoko mo ni ... Nitorina, di okan ninu omo egbe THE WHITE BROTHERHOOD LODGE, egbe anu, ife ati adura, egbe ti adura tini lojo iyara nibiti ... Fun alaye pipe, kowe si: ALABOJUTO P O BOX 64, YABA-NIGERIA.

Ran awon eree lowo Da ehin didun duro

MASE jeki iko-hihu, sinsin didi ... ti ikolu iko ... tabi o-fee fi ojo kan ba orun tabi agbara ilera re je lasiko dan Mendaco ... egbogi ... ni aberegigun tabi ... sugbon ninu eje ni o mise, bayi ni o se de inu odoforo ati awon iho ... yio bere si ... Ekini yio se itantowo ati ... lorun ... Ekeji ... Eketa O nse itantowo ... Mendaco

RA Mendaco lowo apogun loni.

LAKUREGBE LO

Nigbana ni o wipe mo dupe lowo

DeWitt's Kidney & Bladder Pills

Nwon ngmu ... ati apo-ito re fun ise dada ... gbogbo oro ti o nfa

LAKUREGBE, IRORA ORIKE-RIKE ARA ATI EHIN-DIDUN RE JADE

Nigbana, ti irora re o se lo, awon koro egbogi De Witt ni o mu o lokun ati agbara nitori nwon tun eje re se dada. Ra koro egbogi De Witt die nisisiyi ki o si ni ilera ati agbara re pada.

FUN ILERA ATI AGBARA

DeWitt's KIDNEY & BLADDER PILLS
EGBOGI ATEJESE TI GBOGBO AIYE TI MO

OLOTU MI ỌWỌN

Ṣikaṣika gbagbe alajọbi

Olotu,

Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye ninu iwe yin oloyinmọmọ (Irohin Yoruba) lati ṣe alaye diẹ lori egbe Afenifere ati egbe Dọmọnu.

Gbogbo awa egbe Afẹnifẹre ẹdọ ni Shomolu ni ifẹ si Oloye Obafẹmi Awolọwọ nitoripe ni asiko tire, a ri onije je, a ri mu, gbogbo ọna ilu wa lo dara, awọn ọmọde nlọ si ileiwe laisi wahala, nwọn tun fun wa ni ile ejọ ibile, nwọn fun wa ni ile iwosan, nwọn tun kọ ile awọn ọlọpa si Shomolu.

Awọn ọmọ kekeke ngba ogun ni ile iwosan lọfe lai san owo, awọn lyawo nbimọ si ile iwosan. Ile ẹjọ ibile nsiṣẹ ilu lati jẹki awọn enia ilu mọ ofin ati lati ṣọra nipa riru awọn ofin na.

Awọn ole sa kuro ni Shomolu die, iwa tẹmbẹlekun dinku larin awọn enia, alafia si tun wa larin ilu. Egbe Afẹnifẹre se ileri, nwọn si mu ileri na ṣẹ fun ilọsiwaju ilu wa.

Sugbọn nigbati awọn onirikisi egbe Dọmọnu de, nwọn na gbogbo rẹ je, gbogbo ọna arin ilu wa lo ti di kanga ti wọn npọn omi, owo ko si, ọja ko ta, alafia ko tun si larin ilu mọ.

Nipa eyi, bi a ti ngbọ pe egbe Dọmọnu nrinlẹ ni awọn ilu kakiri. wọn ko ni agbara lati fi idi mulẹ ni Shomolu tiwa.

Mo si tun gba gbogbo wa ni iyanju lati ni igbẹkẹle kikun si Oloye Obafẹmi Awolọwọ ki a si tun ma ranti owe ti o so hayi pe, Ṣikaṣika ẹ gbagbe ajobi, adanilọro ọ̀bagbe ọla.

Emi ni,
F. A. Ola. Aderanijoh.
Shomolu.

Titi Oru si Ijẹbu—Igbo baḷumọ

OLOTU, jowo gba mi laye nina iwe Irohin re oloyinmọmọ lati fi kun Igbimo Alabojuto Ijoba Ibile Ijebu-Igbo ki awon yara si atunse ona Oru si Ijebu-Igbo bi owon ko ba wa iparun fun awon ara ilu yi.

Emi-kan ti o ba agbe ilu yi tabi o o lo sibe yio mo wipe ona na buru, o si lewu gidigidi bi o tile je wipe ibuso merin pere ni. Moto ko le gba ona na ki o jagara nitoripe o kun fun koto ati gegele eyi si le fa irubu ati iparun fun oko bi eniti o swa oko ou ko ba mura gidigidi.

Ni lwoni igbati o fi je wipe awon ara ilu yi je asanwo-ori, ti owon si nsan owo-ori won lasiko beni awon ki ise arufin, o ye ki awon oludari Igbimo yi nopinpinda ki awon fun ona yi se ni kiakia.

Bi awon Igbimo yi ba nfe rere pelu awon ara ilu yi, bi nwon ko ba si fe iparun fun won, mo ro awon oludari Igbimo yi lati tete tun ona yi se fun anfani awon eniawon.

Emi ni,
Allinson Agbasale
Ibadan.

IRO IDUNNU FUN AWỌN ATẸWE

O fẹ ṣe atunṣe awọn ohun elo itẹwe (types) rẹ bi?

Bi idahun rẹ ba jẹ bẹni, a jẹ wipe aduro rẹ gba niyẹn nitoripe ẹrọ 'Supercaster' ti o nge biriki itẹwe yio tẹ ọ lọrun laisi wahala

Jẹki African Press Ltd.,
P. O. BOX 78, IBADAN.

TETE GBA Ọ LA NINU IDAMU ITẸWE RẸ

NNDP ṣọ onisẹ Ọba di iransẹ oṣelu

Inu mi yio dun bi olotu iwe Irohin Yoruba bale gba mi laye lati so gbolohun oro mejì tabi meta nipa bi oselu ti nlo ni Aiyedade lekun Ọsun, ati nipa iwa ika ti awon omo egbe Domonu nhu nipa fifi agidi mu enia wo inu egbe won ati nipa dide wole wole si ile awon omo egbe Afenifere nitoripe awon ko lati di egbe Domonu.

Awon aṣiwaju ilu miran ti so ilu siwaju ilu won nu nitoripe ife owo nikan ni won ni lokan, nwon ko nife ilosiwaju ilu rara.

Ninu ẹsun gbogbo ti nwon ona fun ilu awa ko ri nkan kan ni Aiyedade lekun Osun. KI LOWU YIN LORI?

Ko si ina monamona ko si omi, ko si ile ise kankan fun awon omo to ba jade. Ko si ile ifi owo ranse (Post Office) ti o dara.

A fere oda, eko fun wa, oda eyi ti nwon nse lati Ikire de Iwo, gbogbo re lati ba je tan.

Mo ro pe o to asiko lati ronu piwada, bi oju ko ba tiyin' oju nti awa mekunnu ati pe ohun edun okan lo je fun wa.

Olotu, mo dupe fun aye ti e gba mi.

Iwaju ni opa ebiti re si, Iwaju ni owo yin yio ma lo.

Emi ni
R ADEKOLA
Aiyedade

A nfẹ Apoti Ibo ni Ibudo Reluwe

Ẹ gba mi laye lati ṣọ edun okan mi fun Ijọba, ati fun awọn eloto idibo. Inu mi yio si dun bi ẹ ba le tete ba mi tẹ edun okan mi yi jade, ọrọ mi na lọ bayi, ni akoko ikania gbogbo awa osise Reluwe ni Ijoba ka patapata.

Ohun to wa je edun okan mi na nipe lakoko idibo, opolopo ninu awa osise Reluwe ni ki iri aye lo dibo larin ilu nitorina ohun to ye ki Ijoba ba wa se nipa re nipe ki Ijoba jeki apoti idibo wa ni gbogbo ibudo Reluwe ni akoko ibo gbogbogbo to mbo yi.

Eyi yio je irorun fun awa osise Reluwe lati dibo fun Egbe oselu ti kaluku ba fe, bi eyi ko ba si se se, O ye ki Ijoba fun awa osise Reluwe ni aye ni ojo kan fun ojo idibo, mo so eyi gegebi amoran, ki ise gegebi ase o.

Mo dupe aye ti e gba mi Oko oba ko ni sa yin lọse.

Emi ni,
Salami Adesanya
A R O.

Yoruba gbọdọ gbaramu

OLOTU,

Inu mi yio dun ti e ba fe gba mi laye lati so Iba Oro mi yi.

Mo be gbogbo enyin omo Yoruba ki e jeki gbogbo wa fi imo wa sokan ki nwon le ba wa da Baba-Isale wa Oloye Awolowo sile, nitoripe lati igbati nwon ti ju si ewon ni gbogbo nkan ti di ruduru-du, ti owo won ni ilu.

Shobọ ha ku akurun bi ?

INU mi yio dun bi e ba le gba mi laye ninu iwe yin yi Oloyin-Momo, ti o nfi ona han awa ti mo Oduduwa, eyi ti o to loju Oluwa lati se ati ba mi kesi omọ Egba tiletoko, ki nwon ba awa Omọ-Oduduwa wa awon Omọ-Shobọ Arọbi-Odu, Alasaro Oro ri lati ba wa te iwe baba won ti nwon npe ni iwe Shobo jade lekan si.

Nitori ero mi ni pe Ologbe Shobo ko ni ku laini awon eda iwe na ni ipamọ.

Awon alagba si feran lati ma fi iru iwe na se owe pa fun wa ti nwon ba nsọrọ tabi ti nwon ba nkọ wa ni ẹkọ ninu ile. Mo si mo pe iwe yi yio se awa omo Yoruba ni anfani pelu itesiwaju ninu ẹkọ.

Olotu mo dupe aye ti e gba mi, Owo aiye ko ni te yin o. Ase o.

C. Ola Adekusibe
IPONDA II EṢA

Ewo ni Ọmọkowajọ nse ?

Olotu,

Inu mi yio dun pupo ti e ba le gba mi laye die ninu iwe Irohin Yoruba oloyinmomo ti nta bi akara gbigbona loja losose lati bere lowo Oloye Olu Jones Omokowajo, asoju okitipupa ni Ile Igbimo Asofin Ipinle Iwo-Orun ati Alakoso Ijoba ni akoko ti egbe Alakuko ati Ologbe UPP fi nse Ijoba ni Ipinle yi, pe ki o so ibiti o faramo ninu awon egbe mejeji nisisiyi? Boya Egbe Domonu tabi egbe Alakuko, nitoriti o jeri aisan re, o si ti bo lowo ewu nisisiyi.

Ohun ti awa ti a dibo fun ngbo kakiri ko ye wa, a si nfe ki o mu ikuuku kuro loju wa nipa oro na, ki awa le mo ibiti ao rin si.

Nitorina ni oruko gbogbo awa ti a dibo fun wo ile ni Okitipupa, a kesi pe ki o so ti enu re ni kiakia fun awon enia.

Emi ni
Kosoko
Okitipupa

Ibukun Mbẹ Fun Ọrẹ Awo

Olotu iwe Irohin Yoruba, inu mi yio dun bi e ba le ba mi te iwe mi yi sita fun gbogbo aiye gbo. Mo fi iwe mi yi se ileri pe gbogbo enyin ti e ni igbagbọ pe ki Oloye Awolowo wa sile ni yio gba ibukun lehin ti a ba pari lohun.

Mo fe ki olukuluku pa ẹnu re mọ, awon agba ni npowe kan pe "ẹniti o ba mo je eran ki lje edu", ki olukuluku fi ero re si okan di ojo idibo, paapa gbogbo agbalye ni o ti

OLOYE AWOLOWO

mọ pe Oloye Awolowo yio de.

Ori mekunnan ati agbe ni yio da ejo na nigbati ibo didi ba de.

Ori ade ko ni sun nita lailai.

Emi ni
A.A Apotiade
ONDO

Ikire ko Dọmọnu

Olotu, inu mi yio dun ti e ba le ba mi te iwe mi yi jade.

Ọrọ yi ti nje irukan fun mi lati bi osu melo kan sehin ninu ero gbohun gbohun pe tomọde, tagba ni Alyedade ni nwon wa ninu egbe NNDP eyiti gbogbo omọ karo o jire mọ oruko re si DOMONU.

Iro patapata leyi, Oluwa ko ni jeki awa o ba won se ninu egbe buruku, egbe ole. Iwaju lọpa ebiti nre si, iwaju lawa yio si ma lọ ninu egbe Olope.

Jide Akinloye
Ikire.

OJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

I L U	OJO 'RU AUGUST 5 (WEDNESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Obun Eko — — — —
Abeokuta	Ijoko Iberekodo Asu Wasimi —
Ibadan	Ijaiye-orile, Fedegbo, Oyedeji, Egbeda
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishan Isara
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-Odo,
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — — —
Egbado	— — — — — — — —
Ogbomosho	— — — — — — — —
Ekiti	Egosi, Odo-Aiyedun.
BINI	— — — — — — — —
Eti Odo	Kokori
Igbajo	— — — — — — — —
Iressi	ada
Badagry	Obo-Odo Ilogbo-Ale Ad

ILU	OJO 'BO AUGUST 6 (THURSDAY
Eko Ati Agbegbe Re	Mushin
Abeokuta	Otta Abalabi Sodeke Omida Ilawo –
Ibadan	— — — — — — — —
Ijebu	— — — — — — — —
Ijesha	Oshu Itagun Odogbo Idoko Iloko
Ondo Ati Eti Odo	
Egbado	— — — — — — — —
Ogbomosho	Araromi — — — —
Ekiti	Oke Aiyedun
BINI	— — — — — — — —
Eti Odo	— — — — — — — —
Igbajo	Iloro — — — — —
Iressi	
Badagry	Badagry Town

I L U	OJO ETI AUGUST 7. (FRIDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Agege Ikeja Ebute Ero Ikorodu
Abeokuta	Lafenwa, Oba- Obada, Kajola, Ajegunle
Ibadan	———— ——
Ijebu	Ikenne, Okun-owa Erunwon Omu, Mamu, Ibefu Atikori Imushin Ago-woye Ijesha
Ijesha	Esa-Oke Ijebu-Ijesha Ilase Epe Iloba Iperindo Imuroko
Ondo Ati Eti Odo	
Egbado	
Ogbomosho	
Ekiti	Oko — — — - -
BINI	Oke mesi Ifaki Igede Ikole
Eti Odo	Uromi
Igbajo	— — — — — — — —
Iressi	— — — — — — — —
Badagry	— — — — — — — —

I L U	OJO ABAMETA AUGUST 8. (SATURDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo.
Abeokuta	Atan, Agbado, Ifo, Itori, Itoku, Isabo Olode
Ibadan	
Ijebu	Aiyepe, Sagamu, Ita-osu, Ogere, Itele, It Iloti
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	Oka, Ilora.
Egbado	Alagba Ilaro — — — —
Ogbomosho	— — — — — — — —
Ekiti	Ilogbo, Ishan.
BINI	Eke
Eti Odo	Kpaksang, Bomadi, Ekeremor, Toniga,
Igbajo	— — — — — — — —
Iressi	
Badagry	Ojo, Ajido, Iworo

I L U	OJO AIKU AUGUST 9. (SUNDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Obun-Eko.
Abeokuta	Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi, Araro
Ibadan	Ijaiye-orile, Fedegbo, Oyedeji, Egbeda
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishan
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-odo
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — — —
Egbado	— — — — — — — —
Ogbomosho	Egosi, Odo-Aiyedun.
Ekiti	— — — — — — — —
BINI	— — — — — — — —
Eti Odo	
Igbajo	Kokori — — —
Iressi	Obada
Badagry	Ado-Odo, Ilogbo-Ale

ILU	OJO AJE AUGUST 10. (MONDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Mushin
Abeokuta	Otta, Abalabi, Sodeke, Omida, Ilawo.
Ibadan	— — — — — — — —
Ijebu	— — — — — — — —
Ijesha	Oshu Itagun Odogbo Idoko Iloko
Ondo Ati Eti Odo	
Egbado	— — — — — — — —
Ogbomosho	Araromi — — —
Ekiti	Oke Aiyedun
BINI	— — — — — — — —
Eti Odo	— — — — —
Igbajo	Iloro — — — —
Iressi	————————
Badagry	Badagry

I L U	OJO ISEGUN AUGUST 11. (TUESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Agege, Ikeja Ikosi, (Epe).
Abeokuta	Lafenwa Obada Oba Kajola Ajegunle
Ibadan	— — — — — — — —
Ijebu	Ikenne Okun-Owa Erunwon Omu Mamu Ibefun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijesha-Ijebu. Isara Imodi
Ijesha	Esa-oke, Ilase, Epe, Iloba, Iperindo, Imuroko, Ikeji.
Ondo Ati Eti Odo	Igbo-Egunre
Egbado	Oko ————————
Ogbomosho	Oke mesi; Ifaki; Igede; Ikole
Ekiti	— — — — — — — —
BINI	Uromi
Eti Odo	— — — — — — — —
Igbajo	————————
Iressi	
Badagry	

I L U	OJO 'RU AUGUST 12 (WEDNESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo — — — — — — —
Abeokuta	Atan Agbado Ifo Itori Itoku Isabo Odeda Olode
Ibadan	
Ijebu	Aiyepe Sagamu Ita osu Ogere Irolu Itele
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	
Egbado	Oka, Ilara.
Ogbomosho	Alagba, Ilaro
Ekiti	Ilogbo Ishan
BINI	Eke
Eti Odo	
Igbajo	— — — — — — —
Iressi	— — — — — — — —
Badagry	

Alapara Ibadan

(Bere lati oju ewe keji)

yio kun o jẹ bi eran Egungun temi paapa jade ni ọdun yi, ibisi "Alagbara" ni mo nko tantaa pẹlu awọn onilu mi ti nsọrọ bi arira.

Olotu: Bawo ni o se nkọrin na?

Alapara: Orin akọni na ni orin ti awọn onilu mi nko. Bayi ni orin na "Saabodo, Saabada, Akintaku Saabodo Aredọla Saabada, asegisọre Saabada."

Olotu: Kini ha ni itumọ "Saabada"?

Alapara: Awọn ọmọ Ibadan na ni ao bi. Emi gbọ asa na ni mo ada ni temi ni o Alasa lo ni asa. Bi asa kan ti nlọ bẹni omiran nde

Olotu: Nje o mọ nipa ti egungun Ololu Ibadan? Ṣe nigbati ko ba yin da asa ni o fi di egungun ibudo Olọpa?

Alapara: Ki ise asa dida nikan ni ti egungun Ololu. Se bi nigbati ko dọbale fun awọn "alagbara," ti o si niya si ile awọn ọta awọn "alagbara!" Ibadan ni Ololu se bọ si takute wọn.

Olotu: Nje o gbọ ti Ijebu laipẹ yi?

Alapara: Emi ko ri gbọ. Emi wọn paapa ni a jijọ nse egungun Abawula, egungun olokiki ni.

Olotu: Isede ti de ba gbogbo egungun Ijẹbu.

Alapara: Ile pa, Ke wi?

Olotu: Ohun ti mo wi ni o gbọ.

Alapara: Emi yio lo si Ijẹbu lọla lati se iwadi ọrọ na. O tun di ọjọ mẹjọ. A ko ni ri asure pe o.

ILU OMI-ADIO DARU

Akowe ẹka ẹgbẹ Afenifẹre Gusu Iwọ-Orun Ibadan Ogbẹni S. B Coker ti kọ iwe si Ọga ọlọpa Ipinlẹ Iwọ-Orun nipa idamu ti ala,a ẹgbẹ na Ogbeni Lawani Oni-kede nri lati ọwọ awọn ẹgbẹ dẹmọnu.

Akọwe na se alaye bi awọn janduku ẹgbẹ Dẹmọnu se nlọ ikọ le awọn ọmọ ẹgbẹ Afenifẹre kiri, ti awọn si nse ijamba pelu wọn ni Omi-Adio.

Ogbeni Coker so pe awọn ti nsa gbogbo ẹsọn na lo siwaju awọn ọlọpa ibile ti o wa ni Omi sugbọn ko si iyipada-kankan nina iwa janduku ẹgbẹ Dẹmọnu (NNDP).

Asọbade ere bọọlu

HALF—TIME FORECASTS

Newcastle	v	Burnley 2
Watford	..	Oxford U. x
Airdrie	..	Dunfermline 2
Celtic	..	Partick 1
Dundee	..	Dundee U. 1
Falkirk	..	Motherwell 1
Hibernian	..	Third Lanark 1
Kilmarnock	..	Hearts 1
Rangers	..	Aberdeen 1
St. Johnstone	..	St. Mirren 1
Arbroath	..	Albion R. 1
Berwick R.	..	Ayr. 1
Brechin C.	..	Stirling A. 1
Cowdenbeath	..	Forfar x
E S Clydebank	..	Stenhousemuir 2
Hamilton A.	..	Stranraer 1
Morton	..	Dumbarton 1
Queen of South	..	Montrose x
Queens PR	..	Clyde 2
Raith R.	..	E. Fife x

FULL—TIME FORECASTS

Newcastle	v	Burnley x (2)
Watford	..	Oxford U x (2)
Airdrie	..	Dunfermline 2
Celtic	..	Partick T. 1
Dundee	..	Dundee U. 1
Falkirk	..	Motherwell 1
Hibernian	..	T. Lanark 1
Kilmarnock	..	Hearts x (2)
Rangers	..	Aberdeen 1
St. Johnstone	..	St. Mirren 1
Arbroath	..	Albion R. 1
Berwick R.	..	Ayr x (1)
Brechin C.	..	Stirling A. 1
Cowdenbeath	..	Forfar 1
E S Clydebank	..	Stenhousemuir x (2)
Hamilton A.	..	Stranraer 1
Morton	..	Dumbarton 1
Queen of South	..	Montrose 2
Queens Park	..	Clyde 2
Raith R.	..	E. Fife x (2)
Aberdeen (Res.)	..	Rangers (Res.) 2
Dundee U (Res)	..	Dundee (Res) 2
Dunfermline (Res.)	..	Airdrie (Res.) 1
Hearts (Res.)	..	Kilmarnock (Res.) x (2)
Motherwell (Res.)	..	Falkirk (Res.) 1
Partick (Res.)	..	Celtic (Res) 2
St. Mirren (Res)	..	St. Johnstone (Res) 1
Third L (Res)	..	Hibernian (Res.) x (1)

Owe ilẹ Yoruba

Lati Ọwọ Lasisi Okẹ

1 Ojubanire Ọrẹ ko denu Asẹhin deni ko wọpẹ, Sasa enia ni fẹni ba si nile taja tẹran ni fẹni loju ẹni.

2 A ki gba akaka lọwọ Akiti Aki gba ile baba ẹni lọwọ ẹni.

3 Bi o ba fẹ soko ki oyi odo bori ki oso pe enikan ko ri ọ Adakẹ dajọ nwo o loke.

4 Fife lafẹ ewure la sope o dun. Je'ko bi araiye ba nfẹ ẹ mase ro wipe iwọ lo ga ju.

5 Ẹgbẹje irawọ ko le mọlẹ to osupa ohun ti nwani ko le bani lojiji

6 Ẹni a fẹ lamọ ako mo eniti nfẹ ni.

7 Ore pẹ titi nsiwerẹ gbagbe lo da Ifa fun abuke isẹ ki tan, to ni on yio pada si ẹse arọ.

8 Pipe ni yio pẹ akofolo yio pe baba.

9 Ile ni aseni 'gbe ẹhinkule ni ota wa.

10 Ohun ti a ko ba jiya fun se ki pẹ lọwọ. Ohun tẹ a ba fi ẹra se ni pẹ lọwọ ẹni.

11 Enia bi iya ko si, tani o le se ọmọolọmọ lore.

12 Eda ti ko se bi ẹlẹdẹ lọna Ijebu ko le se bi Adegbọrọ loja ọba.

ALỌ O ALỌ

Lati Ọwọ Musibau Bamgbọpa

1 Abiyamọ to bi ọmọ ti ko npọn ọmọ ti rẹ afi tẹniẹni.

2 Odogbo funfun o funfun ni ita, o funfun ni inu o pupa ni arin.

3 Onile mẹta a de ikini ko ni omi, ade ikeji ko ni omi, a de ikẹta a ba omi.

4 Ija kadi ọfa, iya bi ọmọ, ọmọ binu o mu iya na.

5 A go lori a geni idi e ni a fi bi on ba se oro ile baba ẹn.

6 A lẹ mọlẹ o ga juni lọ.

7 O ni segun ti on wo ọlọkunrun, ọlọkunrun ko onisegun ko lọ.

8 Woruku bi igba ọmọ o fi ilẹkẹ kan si won ni idi.

9 A mọ ogiri mẹta, ki ilẹ to mọ ole ti gbe ti arin lọ, ti isalẹ ko 7ẹ, toke ko wo.

10 O yin ni moro, o sa ba ni igba ojo, o gba igbo Ijẹbu lọ pa ọmọ si.

ITUMỌ

1 Esin
2 Eyin
3 Agbọn ti anje
4 Ọmọriodo pelu iya ẹ
5 Igi Paki
6 Agbado
7 Papa ṣiṣe tabi ẹtun Isu
8 Igi Ope
9 Ile eforufu ati Sanmo
10 Agbado

Irohin Yoruba

Inakuna tabua

(Lati ọjọ ewe kini)

NIGBATI a ba ranti wipe ejojemọ ni Ijọba akiṣhe wipe ko si owo, ti nwọn ti nle awọn oṣiṣẹ kuro lẹnu iṣẹ tabi ti nwọn si npa awọn ile iwe keekeke pọ, a ko ni ipinnu meji ju wipe afikun ti o lewu ni afikun awọn Alakoso Ijọba na. Nibo ni ijọba ti e ni Alakoso ijọba bi ọmọ yanxin yi fi itura awọn mekunnu si? TITI mọto ti Ijọba Afẹnifẹre yọ ọba dudu si ni ijọba Akintọla nfi ẹrọfọ tun ṣe lojojumọ yi, bẹni eyi ko to ero fun Oloye Akintọla PẸLU gbogbo iṣẹlẹ wọnyi, ko si ṣoro lati ri kedere wipe Balewa, Bello ati Akintọla ko fẹ mọ boya iran Yoruba parun tabi o wa laye larin awujọ. A kesi awọn enia wọnyi lati dẹkun iwa akami ti o gbode kan ni Ipinlẹ Iwọ Orun loni. Wekeweke ati inakuna wọnyi yio degin lejo kan nitoripe ati ọlẹ ki i kọrakoro ki ile ma yọ.

Ijọ Ọlọrun kọ Fani

IGBIMỌ Ikore ti ṣọọṣi St. Peter's ni Eko fi iwe kan ranṣẹ si Oloye Fani-Kayode laipẹ yi lati fi pe lati wa ṣe alaga ita ọja ikore ṣọọṣi na. Oloye Fani-Kayode na si ti gba pe on yio lọ si ibi ita ọja ikore ṣọọṣi na.

[illegible]

Awọn Ara Eko Taku

[illegible] Oloye Ayọ Rosiji ti awọn ara Eko kan [illegible]

[illegible]

Ade tẹ ṣi Lori Ọni?

Mọkanmọkan ni ẹyọ kan, ẹọ Ọba Kọbọkọbọ ṣe okan gbogbo awọn oba Alaiye Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lokokokan, o ti kuro lori awọn kekeke; o dori awọn agbagba lati owo awọn Igbimọ Afunṣo egbe Dẹmọnu ilu kokan.

OBA ADEREMI

Nisisiyi awọn Igbimọ Afunso Ibile Ile-Ife ti pinnu lati mu agbalagba oba, Ọba Adesoji Aderemi Ọni Ile Ife ti iṣe eni odun mejileladorin kuro lori Itẹ rẹ ki nwọn si wa lọ si agbegbe kan ni Badagry. Ipinnu yi ni o jade ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kini osu kejọ odun yi.

Tele ni osan ọjọ na ni awọn Igbimọ Afunso Ibile Ile-Ife ti ṣe ipinnu pe ki Ijọba mu Ọni Ife kuro lori itẹ, ki nwọn si gba gbogbo agbara lọwọ rẹ.

Nwọn sọ ninu ipinnu wọn pe awọn enia Ile-Ifẹ ko ni igbẹkẹle ninu ọba na mọ nitoripe "o ti kuna ninu ifẹ ti Ọlọrun pẹlu awọn enia rẹ ni si".

Igbimọ na pinnu pe titi ti Ijọba yio fi yọ kuro lori Itẹ rẹ, awọn ko ni san owo osu rẹ fun mọ pẹlu ohunkohun ti oba na ba ni ẹtọ lati gba.

Bayi, Igbimọ na ti pe Ọba Aderẹmi lejo si ile ẹjọ giga kan ni Oshogbe.

Da Ehin didun ati Lakuregbe duro

[illegible]

Igbimọ Akinloye d'okuta mọ ẹru awọn asanwo-ori

—Adisa

[illegible]

Awo

(Lati ọjọ ewe kini)

[illegible]

Alakoso

(Lati ọjọ ewe kini)

[illegible]

Ẹgbẹ Akintọla tẹ lọwọ awọn Abiyamọ

Awọn obinrin ọlọja ni ọja Ẹrekesan ni Ado-Ekiti ti binu fi ọja sile fun awọn Igbimọ Ibile Ado-Ekiti nitori owo goboi ti Igbimọ na bu kun owo ti awọn ti nsan tele.

[illegible]

Classified IKEDE

IWE Iwosan lati ọwọ Ologbe Dokita Odumosu, Ijebu-Ode, (189 pages) Iwe Iwosan gidi, ti ki ṣe aiyederu. Iwe atata ti ọpọlọpọ enia ti nwa. Iwe ijinlẹ. Iwe aje-bi-idan fun iwosan oniruru arun. Price £1: 10: 0d Postage 2/6d. O wa lodọ:- Oloye R. O. Adebonojo, 37, Abeokuta Road, P. O. Box 83, Ijebu-Ode, Telephone: Ijebu-Ode No. 94, tabi Mrs. E. A. Adelaja, Barlgs-Shomolu, Grammar School, P. O. Box 317, Lagos. Telephone: Lagos No 45887 or 45934.

IKEDE PATAKI

IWE ẸRI ẸKA ẸGBẸ AFẸNIFẸRE (ACTION GROUP)

[illegible]

Akọwe eleto egbe
Afẹnifẹre Naijiria.
(Action Group)

Published by the Eastern Post Limited, Elephant House 214 Broad Street, Lagos and Printed for them by the African Press Ltd, P. O. Box 78, Ibadan. Editor: E. O. OLOFIN, c/o 98, Shitta Street, Ibadan.